15. Oluwa ti mu awọn idajọ rẹ kuro, o ti ti ọ̀tá rẹ jade: ọba Israẹli àní Oluwa, nbẹ laarin rẹ: iwọ ki yoo si ri ibi mọ. (Esk 37:26–28; ẹsẹ 5; Isa 54:14.)

16. Ni ọjọ naa a o wi fun Jerusalẹmu pe, "Iwọ má bẹ̀rù: ati fun Sioni pe, Má jẹ ki ọwọ́ rẹ ó dẹ̀. (Isa 35:3,4; Heb 12:12.)

17. Oluwa Ọlọrun rẹ wa ni aarin rẹ, alagbara nì, yoo gba ni la, yoo yọ̀ lorí rẹ fun ayọ̀; yoo sinmi ninu ifẹ rẹ, yoo fi orin yọ̀ lori rẹ." (ẹsẹ 5,15; Isa 63:1; 62:5.)

18. "Emi o ko awọn ti o banujẹ fún àjọ mímọ́ jọ awọn ti o jẹ tirẹ̀, fun awọn ti ẹgan rẹ̀ jásí ẹrù.

19. Kiyesi i, nigba naa mo ni ṣe pẹlu awọn ti npọn ọ loju: emi o gba atiro là, emi o si ṣa ẹni ti a le jade jọ; emi o si sọ wọn di ẹni ìyìn ati olokiki ni gbogbo ilẹ ti a ti gàn wọn. (Isa 60:14; Esk 34:16; Mika 4:6,7.)

20. Nigba naa ni emi o mu yin pada wa, àní ní akoko naa, ni emi o ṣà yin jọ: nitori emi o fi orukọ ati ìyìn fun yin laarin gbogbo eniyan agbayé, nigba ti emi o yi ìgbèkùn yin pada ní oju yin," ni Oluwa wi. (Esk 37:12,21; Isa 56:5; 66:22; Sef 2:7.)

37

# HAGGAI

**(B.C. 520)**

ORI 1.

**Ìpè lati tun Tẹmpili Ọlọrun kọ́.**

NI ọdun keji Dariusi ọba, ni oṣu kẹfa, ni ọjọ ekinni oṣu naa, ọ̀rọ̀ Oluwa wá, nipa ọwọ́ Haggai woli, sọdọ Serubbabeli ọmọ Ṣealtieli, baalẹ Juda, ati sọdọ Jọṣua ọmọ Josedeki, olori alufa, wi pe, (Sek 1:1; 1 Kro 3:17; Esra 3:2; Sek 6:11.)

2. "Bayìí ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi, awọn eniyan wọnyìí nsọ pe, àkókò koiti de, àkókò ti à ba fi kọ́ ile Oluwa." (ẹsẹ 15.)

3. Nigba naa ni ọ̀rọ̀ Oluwa wá nipa Haggai woli, wi pe,

4. "Àkókò ha ni fun yin, ẹyin, lati maa gbe ile ọ̀ṣọ́ yin, ṣugbọn ile yìí wa ni ahoro? (2 Sam 7:2; ẹsẹ 9.)

5. Njẹ nisinsinyìí bayìí ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi pe: Ẹ kiyesi ọ̀nà yin (E.Jer. 3:40.)

6. Ẹyin ti fún irugbin pupọ, ẹ si mu diẹ wá ile; ẹyin njẹ, ṣugbọn ẹyin kò yó: ẹyin nmu, ṣugbọn ko tẹ yin lọrun; ẹyin nbora, ṣugbọn kò si ẹni ti o gbóná; ẹni ti o si ngbowo ọ̀yà o ngba a sinu ajadi apo." (Deut 28:38; Mika 6:14; Sek 8:10.)

7. "Bayìí ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi: Ẹ kiyesi ọ̀na yin. (ẹsẹ 1.)

8. Ẹ gun orí òkè-nla lọ, ẹ si mu igi wá, ki ẹ si kọ́ ile naa, inu mi yoo si dun si i, a o si yìn mí logo, ni Oluwa wi. (Esr 3:7; Psm 132:13,14; Hag 2:7,9.)

9. Ẹyin ti nreti ọ̀pọ̀, ṣugbọn kiyesi i, diẹ ni; nigba ti ẹyin si mu un wá ile, mo si fẹ́ ẹ danu. Nitori kinni? Ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi. Nitori ti ile mi ti o dahoro; ti olukuluku yin si nsare fun ile ara rẹ̀. (ẹsẹ 6; Isa 40:7.)

10. Nitori naa ni a ṣe dá ìrì ọrun duro lori yin, a si dá eso ilẹ duro. (Lef 26:19; Deut 28:23; 1 A.Ọba 8:35.)

11. Mo si ti pe ọ̀dá sori ilẹ, ati sori okè-nla, ati sori ọka ati sori ọti-waini titun, ati sori òróró, ati sori ohun ti ilẹ mu jade, ati sori eniyan, ati sori ẹ̀ràn, ati sori gbogbo iṣẹ ọwọ́ ẹni." (Mal 3:9–11; Deut 28:22; Hag 2:17.)

**Igbọran si ìpè naa.**

12. Nigba naa ni Serubbabeli ọmọ Ṣealtieli, ati Jọṣua ọmọ Josedeki, olori alufa, pẹlu gbogbo eniyan iyoku, gba ohùn Oluwa Ọlọrun wọn gbọ́, ati ọ̀rọ̀ Haggai woli, gẹgẹ bi Oluwa Ọlọrun wọn ti ran an, awọn eniyan si bẹru niwaju Oluwa. (Hag 2:2; Isa 1:19; 50:10.)

13. Nigba naa ni Haggai iranṣẹ Oluwa jiṣẹ Oluwa fun awọn eniyan, pe, "Emi wà pẹlu yin, ni Oluwa wi." (Mal 2:7; 3:1; Matt 28:30; Rom 8:31.)

14. Oluwa si ru ẹmi Serubbabeli ọmọ Ṣealtieli, baalẹ Juda soke, ati ẹ̀mí Jọṣua ọmọ Josedeki, olori alufa, ati ẹ̀mí gbogbo awọn eniyan iyoku; wọn si wá, wọn si ṣiṣẹ ni ile Oluwa awọn ọmọ-ogun Ọlọrun wọn. (2 Kro 36:22; Esra 1:1; 5:2,8.)

15. Ni ọjọ kẹrinlelogun oṣu kẹfa, ni ọdun keji Dariusi ọba.

## ORI 2.

**Àsọtẹ́lẹ̀ nipa ìrànlọ́wọ́ lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun.**

NI oṣu keje, ni ọjọ kọkanlelogun oṣu naa ni ọ̀rọ̀ Oluwa wá nipa ọwọ́ Haggai woli, wi pe,

2. Sọ nisinsinyìí fun Serubbabeli ọmọ Ṣealtieli, baalẹ Juda, ati fun Jọṣua, ọmọ Josedeki, olori alufa, ati fun awọn eniyan iyoku, pe,

3. "Taǹi o kù ninu yin ti o ti ri ile yìí ni ogo rẹ̀ akọṣe? Bawo ni ẹ̀yín sì ti ri i si nisinsinyìí? Ko ha dabi asán loju yin bi a fi ṣe akawe rẹ̀? (Esra 3:12; Sek 4:10.)

4. Ṣugbọn nisinsinyìí mura gírí, Iwọ Serubbabeli, ni Oluwa wi, ki o si mura gírí, iwọ Jọṣua, ọmọ Josedeki, olori alufa; ẹ si mura gírí gbogbo ẹyin eniyan ilẹ naa, ni Oluwa wi, ki ẹ si ṣiṣẹ́: nitori emi wà pẹlu yin, ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi. (Sek 8:9; A.A. 7:9.)

5. Gẹgẹ bi ọ̀rọ̀ ti mo ba yin da majẹmu nigba ti ẹ̀yín ti Egipti jade wá, bẹẹ ni ẹ̀mí mi wà laarin yin: ẹ ma ṣe bẹ̀rù. (Eks 29:45,46; Neh 9:20; Isa 63:11,14.)

6. Nitori bayìí ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi, pe, Lẹẹkan si i, nigba diẹ ni emi o mi awọn ọrun, ati ayé, ati òkun, ati iyàngbẹ ilẹ. (Heb 12:26; Isa 10:25; 29:17; ẹsẹ 21.)

7. Emi o si mi gbogbo orilẹ-èdè, ifẹ gbogbo orilẹ-èdè yoo si dé: emi o si fi ogo kún ile yìí, ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi, (Dan 2:44; Isa 60:4–9.)

8. Temi ni fadaka, temi sì ni wúrà, ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi.

9. Ogo ile ikẹhin yìí yoo pọ̀ ju ti isaaju lọ, ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi: nihinyìí ni emi o si fi alaafia fun ni ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi." (Isa 66:12; Sek 2:5.)

**Mímọ́ ati alaimọ.**

10. Ni ọjọ kẹrinlelogun oṣu kẹsan, ni ọdun keji Dariusi, ni ọ̀rọ̀ Oluwa wá nipa Haggai woli, pe, (ẹsẹ 1,20.)

11. "Bayìí ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi; beere ofin lọwọ awọn alufa nisinsinyìí, pe, (Lef 10:10; Deut 33:10; Mal 2:7.)

12. 'Bi ẹnikan ba rú ẹran mimọ ni iṣeti aṣọ rẹ̀, ti o si fi iṣeti aṣọ rẹ̀ kan akara, tabi àsáró, tabi ọti-waini, tabi òróró, tabi ẹrankẹran, yoo ha jẹ mímọ́?" Awọn alufa si dahun wi pe, "Bẹẹkọ." (Esk 44:19; Matt 23:19.)

13. Haggai si wi pe, "Bi ẹnikan ti o ba jẹ́ alaimọ nipa òkú ba fi ara kan ọ̀kan ninu wọnyìí, yoo ha jẹ alaimọ?" Awọn alufa si dahun wi pe, "Yoo jẹ alaimọ." (Num 19:11,22.)

14. Nigba naa ni Haggai dahun o si wi pe, "Bẹẹ ni eniyan wọnyìí ri, bẹẹ si ni orilẹ-ede yìí ri niwaju mi, ni Oluwa wi; bẹẹ si ni olukuluku iṣẹ́ ọwọ́ wọn; eyi ti wọn si fi rubọ nibẹ jẹ́ alaimọ. (Owe 15:8; Isa 1:11–15.)

15. Njẹ nisinsinyìí, mo bẹ yin ẹ rò lati oni yìí de atẹhinwa, ki a to fi okuta

kan le ori ekeji ninu tẹmpili Oluwa; (Hag 1:5; Esra 3:10; 4:24.)

16. Lati awọn ọjọ wọnyìí wá, nigba ti enikan ba dé ibi ìlé ogún, mẹwa pere ni: nigba ti ẹnikan ba de ibi ìfúntí lati ba aadọta akoto ninu ìfúntí naa, ogún pere ni. (Hag 1:6,9; Sek 8:10.)

17. Mo fi ìrẹ̀dànù ati ìmúwòdú ati yiǹyiǹ lu yin ninu gbogbo iṣẹ́ ọwọ yin: ṣugbọn ẹyin kò yipada sọdọ mi, ni Oluwa wi. (1 A.Ọba 8:37; Amos 4:9; Isa 9:13.)

18. Ni isinsinyìí ẹ rò lati òní lọ de atẹhinwa, lati ọjọ ikẹrinlelogun oṣu kẹsan, ani lati ọjọ ti a ti fi ìpìlẹ̀ tẹmpili Oluwa sọlẹ, ro o. (Sek 8:9.)

19. Èso ha wà ninu abà bi? Lootọ, ajara, ati igi ọpọtọ, ati pomegranate, ati igi olifi, kò ti so sibẹsibẹ: lati oni lọ ni emi o bukun fun yin." (Sek 8:12.)

**Serubbabeli iranṣẹ Oluwa.**

20. Ọ̀rọ̀ Oluwa si tun tọ Haggai wá ni ọjọ́ kẹrinlelogun oṣu naa, pé. (ẹsẹ 10.)

21. Sọ fun Serubbabeli, baalẹ Juda, pe, emi o mi awọn ọ̀run ati ayé; (Hag 1:14; Sek 4:6–10; Heb 12:26.)

22. Emi o si bi ìtẹ́ awọn ijọba ṣubu, emi o si pa agbara ijọba Keferi run; emi o si doju awọn kẹkẹ bolẹ, ati awọn ti o gùn wọn; ati ẹṣin ati awọn ẹlẹṣin yoo wa ilẹ; olukuluku nipa idà arakunrin rẹ̀. (Dan 2:44; Mika 5:10; Sek 4:6; 2 Kro 20:23.)

23. Ni ọjọ́ naa, ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi, ni emi o mu ọ, iwọ Serubbabeli iranṣẹ mi, ọmọ Ṣealtieli ni Oluwa wi, emi o sì sọ ọ́ di Oruka èdìdí kan: nitori ti mo ti yan ọ, ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi." (O.Sol. 8:6; Jer 22:24; Isa 42:1; 43:10.)

38

# SEKARIAH

**(B.C. 519–487)**

ORI 1.

**Ìpè lati ronupiwada.**

NI oṣu kẹjọ, ni ọdun keji Dariusi, ni ọ̀rọ̀ Oluwa tọ Sekariah wá, ọmọ Berekiah ọmọ Iddo woli, pe, (Esra 4:24; Hag 1:1; Neh 12:4,16.)

2. "Oluwa ti binu pupọ si awọn baba yin.

3. Nitori naa iwọ wí fun wọn pe, Bayìí ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi; Oluwa awọn ọmọ-ogun wi pe, ẹ yipada si mi, emi o si yipada si yin, ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi. (Isa 31:6; Mal 3:7; Jms 4:8.)

4. Ẹ má dabi awọn baba yin, awọn ti awọn woli iṣaaju ti ké si wi pe, "Bayìí ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi; ẹ yipada nisinsinyìí kuro ni ọ̀nà buburu yin," ati kuro ninu iwa-buburu yin; ṣugbọn wọn kò gbọ, bẹẹ ni wọn kò feti si ti emi, ni Oluwa wi. (2 Kro 36:15; Hos 14:1; Jer 6:17; 11:7,8.)

5. Awọn baba yin, nibo ni wọn wa? Ati awọn woli, wọn ha wà titi ayé?

6. Ṣugbọn ọ̀rọ̀ mi ati ilana mi, ti mo pa ni aṣẹ fun awọn iranṣẹ mi woli, wọn kò ha tún bá awọn baba yin? Wọn si pada wọn wi pe, "Gẹgẹ bi Oluwa awọn ọmọ-ogun ti rò lati ṣe si wa, gẹgẹ bi ọ̀nà wa, ati gẹgẹ bi iṣe wa, bẹẹ ni o ti ṣe si wa." (Jer 12:16,17; E.Jer. 2:17.)

**Awọn ẹlẹ́ṣin laarin awọn igi mirtili.**

7. Ni ọjọ kẹrinlelogun oṣù kọkanla, ti o jẹ, oṣu Sebati, ní ọdun keji Dariusi, ni ọ̀rọ̀ Oluwa tọ Sekariah, ọmọ Berekiah ọmọ Iddo woli wa, pe,